# Gbígbáradì fún ilé-ẹ̀kọ́

### O lè múra ọmọ rẹ sílẹ̀ fún ilé-ẹ̀kọ́ nípa:

- Ṣíṣe àwọn eré tí ó la ṣíṣe àṣegbà àti ṣíṣe alábàápín lọ
- Ṣerànwọ́ fún un láti béèrè ohun tí ó nílò, tí ebi bá npa á, tí òngbẹ bá ngbẹ ẹ́ tàbí ó rẹ̀ ẹ́.
- Kíkọ́ ọ láti wọṣọ fúnra rẹ̀, jẹun fúnra rẹ̀ kí ó sì fúnra rẹ̀ lọ ilé ìgbọ̀nsẹ̀.




### Bíbẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́ lè jẹ́ ìrírí rere fún gbogbo ènìyàn

- Gẹ́gẹ́ bí òbí, ìwọ ni olùkọ́ àkọ́kọ́ fún ọmọ rẹ.
- Wádìí nípa ilé-ẹ̀kọ́ náà kí o lè lóye ohun tí yóò ṣẹlẹ̀ nígbà tí ọmọ rẹ bá bẹ̀rẹ̀.
- Fi ààyè gba ìbẹ̀wò ilé láti ọ̀dọ̀ olùkọ́ kí ó tó bẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́ tí a bá gbà á wọlé.
- Wo ibùdó-ayelujara fun ilé-ẹ̀kọ́ náà.

Ríi dájú pé o mọ ohun tí ó yẹ láti ṣe ní ọjọ́ àkọ́kọ́: ibi tí ó yẹ láti lọ ní òwúrọ̀, àti ibi tí o ó ti gbé ọmọ rẹ.

**Njẹ́ o mọ̀** pé bí àwọn ọmọdé bá ti nmọjú ilé-ẹ̀kọ́ tàbí jéléósinmi wọn tuntun ní ara wọn yóò balẹ̀ níbẹ̀ sí?

### Ka àwọn ìwé nípa bíbẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ onírúurú ìwé ni ó wà tí o lè ṣe alábàápín nípa ilé-ẹ̀kọ́. Èyí lè ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti ní ìmọ̀lára ìmúra láti bẹ̀rẹ̀ tàbí padà sí ilé-ẹ̀kọ́.

Àwọn ìwé díẹ̀ ni a ṣe àtòkọ sí ìsàlẹ̀ yìí:



- *Starting School* láti ọwọ́ Janet àti Allen Ahlberg
- *Topsy and Tim Start School* láti ọwọ́ Jean and Gareth Adamson
- *Going to School láti ọwọ́ Anna Civardi* àti Stephen Cartwright
- *Harry and the Dinosaurs Go To School* láti ọwọ́ Ian Whybrow
- *Come to School Too, Blue Kangaroo!* Láti ọwọ́ Emma Chichester Clark
- *I Am Too Absolutely Small For School* láti ọwọ́ Lauren Child

### Ṣíṣe àwọn ètò iṣẹ́ tuntun

Ṣe àwọn ètò iṣẹ́ òwúrọ̀ láti jíjí loju oorun, kí a wọṣọ, àti jíjẹ ounjẹ òwúrọ̀ 'lákòókò fún ilé-ẹ̀kọ́' Ríi dájú pé ọmọ rẹ sùn dáradára kí ó sì ṣetán fún ilé-ìwé ní ọjọ́ ákókọ́.

**Olobó oníràwọ̀**
Lópin ọjọ́ náà—kí ọmọ rẹ pẹ̀lú ẹ̀rín kìí síí ṣe ẹ̀rọ alágbèéká!

**Lọ́rọ̀ kúkurú**
Ṣe alábàápín ọ̀kan lára àwọn ìwé tí a tokọ náà. Sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ọmọ rẹ nrò nípa bíbẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́.